NHS

# Dídàbòbo ọmọ rẹ lọ́wọ́ ọ̀fìnkìn

## Ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn ní Orílẹ̀-èdè England

**Ìwífún fún àwọn òbí àti àwọn olùtọ́jú**



**Flu immunisation**

**Síṣe ìrànlọ́wọ́ láti dàbòbo àwọn ọmọ, ní gbogbo àkókó òtútù**

tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 1 30/05/2025 15:46:2

# 5 àwọn èrèdí

## láti jẹki ọmọ rẹ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára



1. **Dabobo ọmọ rẹ**
   Abẹ́rẹ́ àjẹsára náà yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ ààbò fún ọmọ rẹ tako ọ̀fìnkìn àti àwọn ìdìjú lile bíi híhanrun àti òtútù àyà

2. **Dábàbò ọ́, ìdílé àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ.**
   Gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára fún ọmọ rẹ yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ ààbò síi fún àwọn ọ̀rẹ́ àti ìdílé alailagbara

3. **Kò nílò abẹ́rẹ́**
   Imú fínfín kò níra ó sì rọrùn láti gbà

4. **Ó dára jùlọ ju níní ọ̀fìnkìn.**
   Imú fínfín ńṣe ìrànlọ́wọ́ ààbò tako ọ̀fìnkìn, a sì tí fún ọ̀kẹ́ àìmọye ènìyàn ní àgbáyé ó sì ní àkọsílẹ̀ ààbò tó péye

5. **Yàgò fún owó sísan**
   Bí ọmọ rẹ bá ní ọ̀fìnkìn, o le nílò láti gba ààyè kúrò lẹnu iṣẹ tàbí s'ètò ìtọ́jú mìíràn




tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 2 30/05/2025 15:46:3



## Abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn wà l’ọ́fẹ̀ẹ́ fún:

Awọn ọmọ ọdun meji si mẹta (lọjọ 31, osu kẹjọ saaju ki gbigba abẹre ajẹsara to bẹẹrẹ ni igba irẹdanu)





Àwọn ọmọ t’ọjọ ori wọn ti le lọ ile-ẹkọ (Ti wọn n wọle si Ọdun 11)

Àwọn ọmọ t’ọ́jọ́ orí wọn bẹrẹ láti osù 6 pẹ̀lú ipò àìlera kan tó fi wọn sí ewu gíga lọ́wọ́ ọ̀fìnkìn



Ìwífún síwájú síi lórí àwọn ọmọ tó yẹ ní ọdún kọ̀ọ̀kan ni a le rí ní: **www.nhs.uk/child-flu**



tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 4 30/05/2025 15:46:3

## Kíni ìdí tí ọmọ mi fi gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn?

Ọ̀fìnkìn le jẹ́ àìsàn tí kò máyọ̀ wá tó ń́fa ibà, rirẹ gidigidi, isan àti oríkèèríkẹ̀ẹ́ ara ríro, imú dídí, ikọ́ gbigbẹ, àti ọgbẹ́ ọ̀nà-ọ̀fun. Àwọn ọmọ má ń́ saba bẹrẹ lati gbadun laarin bii ọsẹ kan.

Awọn idiju ọfinkin ni híhanrun líle, ìrànmọ́ etí didunni, àti òtútù àyà Àwọn ọmọ kọokan le nilo lati lọ sí ilé-ìwòsàn fún ìtọ́jú, ati ìtọ́jú gidi.

## Kínni àwọn àǹfààní abẹ́rẹ́ àjẹsára?

Níní abẹ́rẹ́ àjẹsára yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti dábòbò ọmọ rẹ lọ́wọ́ ohun tí o le jẹ́ àìsàn búburú nínú àwọn ọmọdé. Àwọn ọmọdé tí wọ kò tii pé ọdun maarun ni ọkan ninu bi a ṣe gba wọn silẹ si ni ile-iwọsan latari ọfinkin.

Yoo din bi awọn yooku ninu idile rẹ, ti wọn le w ani ewu nla lati ọwọ ọfinkin, bii awọn obi agba tabi awọn to ni ipo ilera ọlọjọ pipẹ, kù pẹlu lati ko ọfinkin lọdọ ọmọ rẹ.

O le mu ọ yago fun gbigba aaye lẹnu iṣẹ, tabi awọn iṣẹ yooku, lati tọju ọmọ rẹ to s’aisan tabi bi o ba ṣe aisan funra rẹ.





tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 5 30/05/2025 15:46:3

## Bawo ni abẹrẹ ajẹsara naa ṣe munadoko si?

Abẹrẹ ajẹsara ọfinkin jẹ aabo to dara julọ ti a ni tako aarun aifojuri yii. Aabo ti ọmọ rẹ gba lati ibi gbigba abẹrẹ ajẹsara ti ga si ni sisẹntẹle ju awọn agba lọ.

Ìwọnyí ni orisirisi iru aarun aifojuri ọfinkin ti o si seeṣe ko fa ọfinkin ni a ri siwaju akoko ọfinkin. A ti wa ṣe awọn abẹrẹ ajẹsara lati ṣe deede wọn bi o ti yẹ – wọn yoo saba pese aabo kọọkan koda bi iṣe deede naa ko ba peye.

Àwọn kòkòkò àìlefojúrí ọ̀fìnkìn le pàrọ̀ ara lọ́dọọdun nítorínà à ń mú abẹ́rẹ́ àjẹsára kún ojú òsùnwọn lọdọọdun. Ààbò abẹrẹ ajẹsara naa si le yọ tan to ba ya. Fún ìdí èyí, a dádàá wípé kí ọmọ rẹ tún gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tako ọfinkin ní ọdún yìí, kódà bí o bá gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ọdun tó kọjá.

## Tani yoo fun ọmọ mi ni abẹrẹ ajẹsara rẹ?

Awọn ọmọ ọdun meji ati mẹta (ọjọ-ori ni ọjọ 31 osu Kẹjọ saaju ki gbigba awọn abẹrẹ aj esara to bẹrẹ ni akoko irẹdanu) yoo gba abẹẹrẹ ajẹsara lọdọ Onişegun alabẹ wọn, paapaa julọ nipaṣẹ nọọsi.

A o fun àwọn ọmọ t'ọjọ ori wọn ti le lọ ile-ẹkọ ni abẹrẹ ajẹsara ni ile-ẹkọ, pẹlu anfaani siwaju sii lati gba abẹrẹ ajẹsara, o seeṣe ni ile-iwosan agbegbe, fun ẹnikẹni to ba padanu saa na ni ile-ẹkọ.

A o fun awọn ọmọ to n gba ẹkọ ni ile ni abẹrẹ ajẹsara naa bi wọn ko ba wa ninu ẹgbẹ ọjọ-ori to yẹ. Awọn obi le gba iwifun nipa awọn eto lati ọdọ Ẹka Ẹto Ẹkọ Alaṣẹ Agbegbe wọn.



tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 6 30/05/2025 15:46:3

## Báwo ni a ó ṣe fúnni ni abẹ́rẹ́ àjẹsára náà?

Fún ọpọlọpọ awọn ọmọ, wọn yoo gba a gẹ́gẹ́bi ohun fínfín sí imú. Bi ohun finfin si imu ko ba wulo fun ọmọ rẹ, a le fun ni abẹrẹ kan dipo, paapajulọ sinnu isan ni oke apa.

## Báwo ni ohun fínfín sí imú ṣé ń sişe?

Ohun fínfín sí imú ní àwọn kòkòkò àìlefojúrí tí kò lágbára láti dènà wọn láti fa ọ̀fìnkìn sùgbọ́n yóò ràn ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti ní àjẹsára. Eyi tumọ si wipe ọmọ rẹ yoo le gbogunti ọfinkin daradara.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára má ń tètè sínlẹ̀ ní imú, kódà bí o bá sín lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ lẹ́yìn tí o bá ti fín, o kò nílò láti fòyà pé kò tíì sişé.

## Ǹjẹ́ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí wà bí?

Awọn ọmọ le máa s'omi ní imú tàbí kí imú wọn dí, orí fífọ́, ara rírẹ̀ gbogbogbo àti àìle jẹun. Ẹ̀wẹ̀, àwọn wọ́nyí kò le rárá ju níní ọ̀fìnkìn tabi awọn ìdíjú to sopọ mọ ọfinkin. Àwọn ìdíjú líle kò wọ́pọ̀.

## Njẹ abẹrẹ ajẹsara naa le fa ọfinkin?

Bẹẹkọ, abẹrẹ ajẹsara naa ko le fa ọfinkin nitori awọn kokoro aarun aifojuri to wa ninu rẹ ko lagbara lati ma jẹki eyi waye.



tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 7 30/05/2025 15:46:3

## Bi ọmọ mi b ani ipo ilera kan nkọ?

Awọn ọmọ toni awọn ipo ilera kọọkan, koda ti a ba mojuto wọn daadaa, wa ni ewu giga awọn idiju lile bi wọn ba ni ọfinkin. O ṣe pataki gidigidi ki awọn ọmọ wọnyi gba abẹrẹ ajẹsara.

Àwọn ipọ̀ wọ̀nyí ni:

- awọn isoro ẹdọ foro lile, fun apẹẹrẹ, ikọ ife to nilo mimi lemọlemọ tabi steroids lilo
- àwọn ipò ọkàn líle
- ààrùn kídìnrín tàbí ẹ̀dọ̀
- itọ suga
- àìlágbára ìkẹ́ẹ̀kọ́
- ajẹsara to lọọlẹ gidigidi latari aarun ati itọju, fun apẹẹrẹ, itọju ilera kẹmotẹrapi (chemotherapy) tabi radiotẹrapi (radiotherapy) fun aarun jẹjẹrẹ tabi ilo steroid fun igba pipẹ
- àwọn ìsòro pẹ̀lú ọlọ inú, boya nitoripe a ti yọ ọlọ kuro (asplenia) tabi ko siṣẹ daradara, fún àpẹrẹ, ààsàn arunmọlégun, tàbí tí a ti yọ ọlọ inú kúrò
- dokita rẹ tun le daba wipe ọmọ rẹ ti gba abẹrẹ ajẹsara bi wọn ba ni ipo kan ti n koba eto iṣedara ara bii aarun ọpọlọ-ẹyin





tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 8 30/05/2025 15:46:4

Awọn ọmọ wọnyi gbọdọ gba abẹrẹ ajẹsara lọdọọdun lati ọjọ-ori osu mẹfa soke. Ọpọ yoo gba abẹrẹ ajẹsara oni finfin siu mu sugbọn a ko daba rẹ fun awọn ọmọde ti wọn ko tii pe ọdun meji l’ọjọ ori.

Awọn ọmọ ti wọn ko tii pe ọdun meji, ati awọn ti ohun finfin si imu ko ba lara mu fun awọn eredi iṣegun, yoo gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin gígún.

Bi ọmọ rẹ ba ni eyikeyi ipo ilera ti a kojọ lori oju-ewe kẹjọ sugbọn ko jẹ ọkan lara awọn ẹgbẹ ọjọ-ori to gba abẹrẹ ajẹsara ni ile-ẹkọ, o ṣe pataki ki o kansi dokita rẹ lati s’eto ipade kan.

Bi o ba ni awọn ibeere siwaju sii, ba nọọsi, GP tabi ikọ ilera rẹ sọrọ.

## Báwo ni a ó ṣe gba abẹ́rẹ́ àjẹsára?

Fun awọn ọlọjọ ori meji ati mẹta, o gbọdọ gba ipe ki ọmọ rẹ to le gba a ni ọdọ dokita alabẹ wọn ni igba irẹdanu. Lọna miiran, o le kansi wọn taara lati s’eto ipade kan.

Àwọn ọmọ t’ọjọ ori wọn ti le lọ ile-ẹkọ akoko gbigba abẹrẹ ajẹsara yoo waye ni ile-ẹkọ laarin saa igba irẹdanu. Ikọ̀ ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ti ilé-ẹ̀kọ́ yoo kansi ọ lati ile-ẹkọ.

Bi ọmọ rẹ ba wa ninu ẹgbẹ to yẹ lati gba abẹrẹ ajẹsara ni ile-ẹkọ ti o si ni ipo ilera to fi wọn si ewu ọfinkin giga (wo oju-ewe 8), o le bi dokita alabẹ ọmọ rẹ leere lati pese abẹrẹ ajẹsara bi o ko ba fẹ duro de akoko gbigba abẹrẹ ajẹsara ti ile-ẹkọ tabi bi eyi ba jẹ ohun ti o yan laayo.





tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 9 30/05/2025 15:46:4

## Ǹjẹ́ awọn ọmọ kankan wà tí kò gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára imú?

Gẹgẹbi awọn ipo ilera awọn ọmọ lọwọlọwọ ti le jẹ alaigbara si awọn idiju ọfinkin o ṣe pataki wipe wọn gba abẹra ajẹsara. Awọn ọmọ le ma le gba abẹrẹ ajẹsara onimu bi wọn ba:

- bá ńmí lemọ́lemọ́ lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí ti ní ìrírí mímí lemọ́lemọ́ ní wákàtí 72 sẹ́yìn, a gbọdọ fun wọn ni abẹrẹ ajẹsara ọfinkin lati yago fun idaduro aabo
- ti nilo itọju gidi latari
  - Ikọ ife tabi
  - aibaramu ẹyin anaphylaxis

  (Awọn ọmọde ninu isọri mejeeji yii ni a daba imọran fun lati beere imọran lọwọ akọṣẹmọṣẹ wọn wọn si le gba imọran lati gba ajẹsara onimu ni ile iwosan)
- ni ipo kan, tabi wa lori itọju, to ma n din eto ajẹsara ku tabi ni ẹnikan ninu ile to nilo iyẹrasapakan nitoripe wọn ni ajẹsara to lọọlẹ gidigidi
- ni aibaramu si awọn eronja abẹrẹ ajẹsara miiran*

Bí ọmọ rẹ ko ba le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn oní fínfín o gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn nípa abẹ́rẹ́ gúngún.

Bí kò bá dá ọ lójú, ṣe àyẹ̀wò pẹ̀lú ikọ̀ ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ti ilé-ẹ̀kọ́, tàbí nọ́ọ̀sì àbí GP ní àkókò iṣẹ́ abẹ rẹ.



tect your child against flu - primary or pre-school - Yoruba.indd 10 30/05/2025 15:46:4

Àwọn ọ̀dọ́ tí wọ́n ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú gbọ́dọ̀ yàgò fún ìfarakanra pẹ̀lú àwọn ènìyàn tóní iṣẹ́-ara tí kò l'ágbára (fún àpẹrẹ àwọn tó sẹ̀ṣẹ̀ ṣe ìpàárọ̀ mùdúnmúdùn eegun) fún bíi ọ̀sẹ̀ méjì tó tẹ̀lé gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára.

## Njẹ awọn ọmọ mi le gba ajẹsara ọfinkin nigba kanna bii awọn abẹrẹ ajẹsara yooku?

Bẹẹni. Wọn le gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin lẹẹkanaa gẹgẹbi gbogbo eto abẹrẹ ajẹsara ọmọde. A le dá abẹ́rẹ́ àjẹsára náà dúró bí o bá ní ibà. Bakannaa, bí o bá ni imú dídí tàbí imú tó ń s'omi gidigidi, o le dí abẹ́rẹ́ àjẹsára lọ́wọ́ láti wọ ara rẹ. Ní irú èyí, abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn le jẹ̀ súnsún síwájú tító tí àwọn ààmì àìsàn imú fi kúrò. Nígbà mìíràn a le gún abẹ́rẹ́ àjẹsára sínú ara rọ́pọ̀.



*Wo oju-ewe ayelujara ni **www.medicines.org.uk/emc/product/15790/smpc** fun akojọ awọn eronja abẹrẹ ajẹsara

## Ǹjẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára imú ní gẹlatini tí a gbà nínú àwọn ẹlẹ́dẹ̀ (porcine gelatine)?

Bẹẹni. Abẹ́rẹ́ àjẹsára imú ní gẹlatini to keere gan lati ọdọ awọn ẹlẹdẹ (porcine gelatine), èyítí a ti lò ní fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ òògùn pàtàkì. Gẹlatini náà ńràn ọ lọ́wọ́ láti múkí àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà dúró kí o ba le sisẹ daradara.

Ohun fínfín sí imú jẹ abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a yàn laayo fun awọn ọmọ, o si má ń tètè ati rọrun lati funni. O si le dara gidigidi ni dindin titan ofinkin kiri ku ni agbegbe. Bi o ko b agba awọn oogun tabi abẹ́rẹ́ àjẹsára to ni gẹlatini porcine ninu, abẹ́rẹ́ àjẹsára ọfinkin kan ti ko ni gẹlatini ninu wa larọwọto.

## Níbo ni mo ti le gba ìwífún síwájú síi?

Ṣe àbẹ̀wọ̀ sí **www.nhs.uk/child-flu** fún ìwífún síwájú síi. Bi o ba ni awọn ibeere siwaju sii, ba dokita, nọọsi, nọọsi ile-ẹkọ ọmọ rẹ tabi olubẹwo ilera rẹ sọrọ.

NHS

**www.nhs.uk/vaccinations**

© Crown copyright 2025. UK Health Security gateway number: 2024861.
Product code: 2025FCYO Yoruba. 1P 7K May 2025 (APS).
To order more copies of this guidance please visit:
www.healthpublications.gov.uk or call 0300 123 1002.
That this leaflet is available in, Albanian, Arabic, Bengali, Bulgarian, Chinese (simplified), Chinese (traditional, Cantonese), Estonian, Farsi, French, Greek, Gujarati, Hindi, Latvian, Lithuanian, Nepali, Panjabi, Pashto, Polish, Portuguese, Romanian, Romany, Russian, Somali, Spanish, Tagalog, Turkish, Twi, Ukrainian, Urdu and Yiddish.
Accessible versions are also available as an English large print, braille, British Sign Language video and audio version.